CORESPLEN
OGUN OSI PATAKI
OGUN YI DARA PUPO PAPA FUN OMODE FUN OSI TABI AKAN-INU, JIRUNJIRUN, ORERE, AFUN, ARUN IBA, IGBONA FOFO, AIPERI, AILEJEUN, AILEJE LARA ATI BEBE.


# Irohin Yoruba

A Newspaper of the Amalgamated Press (of Nigeria) Ltd

VOL. XIV NO. 691. SEPTEMBER 1—SEPTEMBER 7, 1958. KOBO MEJI (2D.)


**Lakaye oro**

"Ẹ maṣe gbẹkẹ nyin le awọn ọmọ-alade, ani le ọmọ-enia lọwọ ẹniti ko si iranlọwọ. Ẹmi rẹ jade lọ, o pada si erupe, li ọjọ na gan an, ero inu rẹ pin."

# MEJE NINU AWỌN FỌ'LE-FỌ'LU IBADAN GBA IDAJỌ IKU

**IBADAN—Ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kọkandinlọgbọn oṣu ti o koja yi ni Adajọ-agba Kotu Ganran, Ibadan, Ogbẹni Richard Ade. Doherty da ẹjọ iku fun awọn meje ninu awọn fọ'le-fọ'lu Ibadan ti nwọn pa Ṣuara Akanmu Onikẹde, ẹni ogoji ọdun ni abule Onikẹde ni Ibadan nigbati nwọn nja ija-igboro ti nwọn ja lẹhin iku Alhaji Adegoke Adelabu ti iṣe Aṣiwaju Ẹgbẹ Alatako Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ni igba aiye rẹ.**

Awọn ọdaran apania meje na ti nwọn dajọ iku fun ni:—Busari Arẹmu, (ẹni ọdun mẹrinlelogbọn) Alaga Ẹka Ẹgbẹ Alakuko (NCNC) Iddo; Oduọla Akintọla, ẹni ọdun mejilelogoji) Akọwe; Salawu Adedigba, ẹni ọdun mọkandinlogọta; Ẹmilọla Adeyẹmi (ẹni ọdun mejilelogbọn); Lasisi Adisa (ẹni ọdun mọkandilogoji); Murainọ Adio (ẹni ọdun mejilelogbọn) ati Adeleke Arutu, ẹni ọdun mọkanlelogoji.

Idajọ na fere gba Adajọ-agba na ni wakati meji (100 minutes) ki o to o ka a tan. Die ti aye wa fun lati kọ 'nu awọn alaye rẹ na ni pe o ni on ri ẹri daju pe awọn ọdaran apania meje yi ni o pa Suara Akanmu Onikẹde, o ni ki iṣe wipe nwọn ṣeeṣi pa a ninu ija-igboro na ni, ṣugbọn nwọn di i lọwọ di i lẹsẹ mu, nwọn da ọbẹ de e lorun, nwọn dumbu rẹ bi ẹran Ileya ni.

Awọn ọdaran apania meje ti o gba idajọ iku yi jẹ ọwọ kan ti nwọn kọkọ ṣe idajọ wọn ninu awọn ọdaran apania mẹrindinladọrun ti nwọn mu ẹjọ won lọ si Kotu Ganran. Bi nwọn ba si ti ṣe ẹjọ awọn yoku si, ẹ o ma a gbọ. Ṣugbọn Ogbẹni Majeed Agbaje ti iṣe Agbẹjọro awọn apania meje ti nwọn da ẹjọ fun yi sọ wipe on tun fẹ gbe ẹjọ na lọ si Kotu Kotẹmilọrun.


Ogbẹni Richard Ade. Doherty, Adajọ Agba Kotu Ganran, Ibadan.

## Ẹlẹwọn kan bu Oni-fọto wa jẹ ni Kotu

EKO.

Ni ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kọkanlelogun oṣu ti o koja yi ni ogbologbo apẹlẹwọn kan Jacob Akintunde ti Adajọ-agba Kotu Kekere Yaba ju si ẹwọn ọdun mẹta oniṣẹ aṣekara fun ẹsun ile-fifọ ati ole-jija foromọ Ogbẹni Alfred Desalu, oni-fọto Ile-iṣẹ "Daily Service" ati Iwe "Irohin Yoruba" o si ja a jẹ yannayanna ni ẹhin.

Nigbati Adajọ na ju u sẹwọn tan ti awọn olopa mu u kuro ninu apoti ti nwọn ngmu u lọ si ọgba ẹwọn ni oni-fọto wa ba fẹ ya fọto rẹ, bi o ti ri i pe on ni o fẹ ya ni o ba foro mọ ọ lorun ti o bu u jẹ lẹhin, opelope awọn ọlọpa iba bujẹ pa ni. Ṣugbọn onifọto wa si ti lọ toju ara rẹ ni Ile-iwosan, o si ti gbadun.

Awọn ọlọpa ti tun lọ mu u lọgba ẹwọn lati wa ba a ṣ'ẹjọ bubujẹ ti o bu onifọto wa jẹ na, gbogbo aye bi Dọkita si ti ṣe itoju oju-ọgbẹ ẹhin na si ni awọn ọlọpa t gba sọwọ lati fi ba wijọ, bi nwọn ba si ti pari ẹjọ na si ẹ o tun ma a gbọ.

# Akintọla lọ si Ilu Oyinbo

EKO.

Ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹrindinlogbọn oṣu kẹjọ ọdun yi ni Oloye S. L. Akintọla, Gbakeji Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) ati Minista Alamojuto Ile Iṣẹ Waya ati Ọkọ-ofurufu fun Apapọ Ijọba Naijiria ati Iyawo rẹ ati ọmọ wọn ọkunrin, ọmọ ọdun meje ba ọkọ elefin lọ si ilu Oyinbo. Ọkọ kanna ni on ati Dọkita Azikiwe, Olori Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ati Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun jọ wọ. Opọlọpọ awọn enia pataki pataki ni o sin wọn de Apapa.

Ki Oloye Akintọla to wọ ọkọ, o sọ fun awọn aṣoju iwe irohin ni Ebute-ọkọ, ni Apapa pe inira nla-nla ni awọn Oluwadi iberu awọn ẹya ilu kekeeke Naijiria sọ ọran awọn ẹya ilu ti nwọn ṣe iwadi nipa iberu wọn da. O ni awọn gbe nkan gbẹhin awọn ẹya ilu keekeke Ipinlẹ Iwọ-Orun ati Ipinlẹ Ila-Orun kọja. Oloye Akintọla ni nwọn ko ṣe nkankan fun Ipinlẹ Ariwa lori ọran yi, o ni bẹẹni Ipinlẹ Ariwa pọju awọn ipinlẹ mejeji yi lọ, o si bere pe "Njẹ inira kan tun wa fun awọn ara ilu ti o ju eyi lọ?" O ni dipo ki awọn Oluwadi ṣe eto ti yio tun nkan ṣe ti yio mu iberu awọn ẹy. ilu na kuro nṣe ni nwọn da gbogbo rẹ ru ti nwọn si mu gbogbo rẹ ṣoro lati tunṣe.

Oloye Akintọla yio lo ọjọ diẹ ni Londọnu lati ba wọn pari eto ori aṣeyẹ ti nwọn fẹ ṣe ni ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kini oṣu kẹwa ọdun yi fun iranti ọjọ ti nwọn da iṣẹ ọkọ-ofurufu Naijiria (Nigerian Airways) silẹ, yio si simi fun igba diẹ ki o to lọ ba awọn Ikọ Naijiria ṣe ipade. Gbara ti nwọn ba ti mu u wa si opin ni yio gbera lọ si Kanada ati United States of America fun abẹwo Ile-iṣe Ọkọ-ofurufu "Flying Schools" ati awọn Ẹgbẹ "Flying Clubs" lati le pari eto bi nwọn yio ti ṣe da awọn "Flying Schools" ati "Flying Clubs" ti Naijiria silẹ.


Oloye S. L. Akintọla pelu Iyawo rẹ


Awọn taya ti o darajulọ fun ilẹ Naijiria...

MICHELIN "SDS" fun aye ere sisa ni iwọn iba

MICHELIN "X" fun aye ibiti ere sisa ba s:ro




MICHELIN TYRES

Awọn alagbata ni SCOA—CFAO

# Enyin ọmọ ilu Okuku, ẹ tẹ sibi t'aiye tẹ si

E JỌWỌ gba mi laye diẹ ninu Iwe "Irohin Yoruba" ti o jẹ agbonrandun gbogbo ọmọ Yoruba paapa julọ fun gbogbo Naijiria lati ba awọn ọmọ ilu Okuku damoran lakaye lori ọran ilu wa Okuku.

Aye ti ilu Okuku wa ko ye ki a 'i ọmọ Okuku nibẹ ti yio ma se Ẹgbẹ Alakuko. Lati ọjọ ti a ti ngbọ irohin awọn Ẹgbẹ Oṣelu bi nwọn ti ṣe eto ilu si, a ko gburo pe Ẹgbẹ Alakuko (ẹni-esin-ẹni-sin) ṣe eto rere si ilu kan ri.

Nipa bayi e jẹki gbogbo wa so ọwọ lu ki a di Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) mu. bi enia ba si jẹ ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre ibikibi ti o ba de ni nwọn o ma a fi oju ọmọluabi wo oluwarẹ yatọ si ki awọn ma a fi oju fọ'le-fo'lu wo o bi ti ọmọ Ẹgbẹ Alakukọ.

Nitorina mo bẹ gbogbo ẹnyin ọmọ Okuku ti o wa ni ile ati ni idalẹ ki ẹ fi imọṣọkan pelu awa ti a wa l'Oke Okun (Ghana) ti a ti di Ẹgbẹ Afẹnifẹre lati ja fun idagbasoke ilu wa, inu ifimọṣọkan ni agbara da. Ẹ jẹki a tẹ si ibi aiye tẹ si, ọdọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni igbala Naijiria wa, nitorina ẹ jẹki gbogbo awa ọmọ Okuku faramọ Ẹgbẹ Igbala-ilu o.

Emi ni,
G. B. A. OLOWOLAGBA
Ashanti Akim,
Ghana.

# Iwe si Olotu Irohin Yoruba

## Idahun si ibere Ezekiel Idowu

INU mi yio dun bi Olotu ba le gba mi laye lati dahun si ibere Ọgbẹni Ezekiel Idowu, ti o jade ni oju ewe keji Iwe "Irohin Yoruba" ti ọjọ Aje ti ise ọjọ kọkanla osu yi pe:—"Kiniṣe ti oruko Mọmọdu ko fi si ninu Bibeli?"

Idahun temi ni pe:—Nigbati o di ọgbọnwodinlẹgbẹta odun (570 years) ti Jesu ti ku ti o si ti jinde ti o si ti goke lọ si ọrun ni a to bi Anọbi Momodu s'aiye, nigbati o di ẹgbẹta ọdun o le mẹwa (610 years) ti Jesu ti goke lọ s'ọrun ni Anọbi Mọmọdu to dagba to lati ma a wasu gẹgẹbi Ojiṣẹ Ọlọrun. Awọn ti o nkọ Ihinrere ti a fi pari ọrọ inu Bibeli si ti pari kikọ rẹ tan.

Nitori idi eyi ni ko ṣe si orukọ Anọbi Mọmọdu ninu Bibeli. Idi rẹ ti oruko Jesu fi wa ninu Al-Kurani ni wipe ki nwọn to kọ Al-kurani ni nwọn ti mọ itan Jesu Kristi dada ati ti awọn Woli ati awọn Ọba miran ninu Bibeli pelu. idi eyi ni o jẹki a ma a ri oruko gbogbo wọn ninu Al-Kurani.

Mo dupẹ aye ti Olotu gba mi.

Emi ni,
Kọlawọle Akanni Ṣokunbi.
Itoko-Abẹokuta.

## Tani o gbọn, tani o si gọ ju ninu awọn mejeji yi?

INU mi yio dun ti ẹnyin onkawe "Irohin Yoruba" ba le sọ fun mi ninu idahun nyin fun ibere yi pẹlu alaye kikun nipa ẹniti o gbọn tabi ẹniti o gọ ninu awọn mejeji ti mo fẹ sọ ita wọn yi.

**AGBẸ ATI ỌBỌ**

Ni ọjọ kan agbẹ kan dide o lọ ṣan igbo, o si fi da oko agbado. Ṣugbọn bi o ti nṣan igbo yi, ti o sun igbẹ ti o si kọ ebe, ti o si gbin agbado ni ọbọ kan dakẹ sinu igbo ti o nṣọ ọ. Ṣugbọn nigbati agbado dagba tan ti o y'ọmọ ti agbẹ yi nreti ki agbado na gbo dada ki on to ya a ni ọbọ yi ba ya gbogbo rẹ jẹ larin ọsẹ meji ti oloka na ko fi wa sibẹ. Ẹ jọwọ ẹ la a ye mi, tani ọlọgbọn, tani omugọ ninu ọbọ na ati oloko na?

Olotu mo dupẹ aye ti ẹ gba mi.

Emi ni,
SHITTU A. ADESHIYAN
P. O. Box 0/05,
Takoradi—Ghana

## Nwọn ko ha fẹ ki a ko ere oko de ile ni?

OLOTU, ẹ jọwọ gba mi laye lati fi ọrọ yi han awọn Olotu Ijọba bi nwọn ba le ba ni ṣe iranwọ rẹ Iranlọwọ ti a nfẹ na ni pe bi awa ti a wa l'Oke Okun ba mbọ wa si ilu wa (Naijiria) awọn Onibode a ma a gbowo lori nkan eelo wa bi ẹwu tuntun, fila, ṣokoto, agogo-isomọwọ, ti ori tabili ti a ba fẹ ma a lọ lo nile fun anfani ara wa, ti ki iṣe ọja tita rara

Awọn baba wa ni i ma a ṣadura wipe, "ki Ọlọrun jẹki ero oko ko ere dele" a ha le ma a ṣiṣẹ ni idalẹ ki ọran a ti ra nkan elo lọ sile fun anfani ara ẹni di akanti bi o, nitori awọn oṣiṣẹ-onibode? Nitorina a bẹ Ijọba lọpọlọpọ ki nwọn ba wa ri si ọrọ na ki nwọn si ran wa lọwọ, ki o le fi jẹ pe lori ọja-tita nikan ni awọn Onibode yio ma r gba owo le lori

Olotu mo dupẹ aye ti ẹ gba mi

Emi ni,
NASIRU AJIṢAFẸ.
Kumasi-Ghana.

## Kiniṣe ti a ko gbohun Ọmọbokun ninu redio mọ?

O YA ni iyanu pe a ko gbohun ỌMỌBOKUN "Apalọ-p..-kisa" ninu ẹrọ asọrọmagbesi mọ lati ọjọ pipẹ. Ohun ti o mu mi bere ni pe gbogbo wa ni a ngma a gbadun itan orisirisi ti i ma a sọ. Eko ti o si ngma a wa ninu awọn itan rẹ na pọju adun inu wọn lọ.

E jọwọ, ẹnyin Alakoso Ile-iṣẹ Asọrọmagbesi, ẹ la a ye wa? Ki a le mo ohun ti o fa idi rẹ ti a ko fi gbohun obirin na mọ. Bi a ba gbọ idi rẹ, boya a le ri ọrọ sọ si i ninu Iwe "Irohin Yoruba" Bi Ọmọbokun paapa ba si ri iwe yi ka ki o jẹki a mọ lati ọdọ on paapa, kiniṣe ti a ko fi gbohun rẹ ninu ẹrọ Redio mọ?

A dupẹ o.

Emi ni.
Y. AYINLA DISU.
Eko.

**AKIYESI:—Awọn ti nwọn tun kọ iwe wa pe ki a ba wọn bere pe kiniṣe ti a ko fi gbohun Ọmọbokun ninu Redio bakanna bi ti Ọgbẹni Disu yi ni Oseni Ọjẹwalẹ, Ile Asalu, Ọyọ ati Salami Okunọla, Abule Ogunlade, Ajilete.**




FUN AGBARA
ATI OKUN

Nje irewesi, are ati aisan mu nse ọ l'ẹkọkan? Bi o ba ribẹ, eyi ni ohun ti o nilati ṣe. Mu Egbogi Phosferine Tonic Wine lojojumọ. O nmu ki ọkunrin tobi ki o si sigbonlẹ. O nfun obinrin ni agbara ati ilera. Yio fun awọn iṣan ara re li agbara, eyi yio si jẹki o sun gbadun ki si ji didi pẹlu idunnu. Ra Egbogi Phosferine Tonic Wine yi l'oni gangan. Egbogi atata ni eyi.




PHOSFERINE
TONIC WINE

*agbo ti o gbadun . . .
mejetitun nla – yio se o ni ire.*




OLOGBON ENIA
NGUN RALEIGH

Ọlọgbọn enia ki irin arinwọdi. A ma gun Raleigh a si ma kakiri pelu irorun lai na owo kankan. A ma gbe eru wiwuwo pelu idera. O le k'owo jọ lọpọlọpọ.

O GBỌDỌ *gun Raleigh*

GBOGBO IRIN KẸKẸ
RALEIGH
LO RỌ

# AWORAN ONITAN





# Irin ajo mi si awọn Ilu Gẹẹsi, Kanada ati Amẹrika (4)

## Latı ọwọ J. G. Aceniran, Ibarapa-Ibadan



J. G. ADENIRAN

(Wọn ajo ẹwe kewa)












## Alfaqihi Oshishi ba awọn "Muslim Scout" sọrọ ẹkọ

EKO.

LENULOLOYI ni ẹsẹ awọn Egbẹkunrin "Muslim Scout" pe ṣoṣọ si Gbongan "Zumratul Islamiyyah School, ni Adugbo Akanni l'Eko lati gbọ ọro ti o mu ẹko dani ti Alfaqihi Tairu ba wọn so.

Alfaqihi na ṣe alaye ninu ọro rẹ pe Oluwa ko da ẹda enia si aiye lasan. O da a lati ma a ṣe iṣẹ ti o dara ni. O ni Oluwa pa a laṣẹ sinu Iwe Musulumi Mimọ (Alkurani) 18, ẹsẹ 7 pe ki a ma a sa gbogbo agbara wa fun anfani ati igbega ilu wa. O ṣe wọn ni iranti pe awọn ọmọ enia ti fi ifẹinu wọn se ipinnu niwaju Ọlọrun ati enia lati ma a ṣiṣẹ rere ati lati ma a yin Ọlọrun logo. O si tun ṣe alaye ninu ọro rẹ bi Ọlọrun ti ṣe so pe, fun anfani enia ni On ti ṣe da awọn nkan elo si aiye.

Alfaqihi Tairu Oshishi ṣe alaye kikun ninu ọro rẹ na bi aya Anabi Mohanmed (ki ikẹ Ọlorun ma a ba titi lailai) ti ṣe irohin ọkọ rẹ dada s'. Alfaqihi sọ pe ni gbogbo aye ni Anabi na fi jẹ ọmọluwabi. O ni olufọkansin ni i ati pe Oluwa da a ni awokọṣe enia.

O fi akanṣe adura mu ọro ẹkọ rẹ wa si opin, awọn "Scout" na si dupẹ lowo rẹ pupọ, fun ẹkọ ti o fun wọn.

## R. A. Oguns kọmọjade

Ajegunle-Itamọ lẹba Abẹokuta:—

NI ọjọ Iṣegun ti iṣe ọjọ karun oṣu yi ni Ọlorun fi ọmọkunrin kan ta Ọgbẹni R. A. Oguns pẹlu iyawo rẹ, Moriamọ Amope lorẹ, nwọn si ṣe ikomọjade ni ọjọ kẹjọ ti nwọn bi i ni ọna ẹsin Musulumi Alfa Ganiyu ti Abule Panu ni o ṣe isin isọmọloruko na. Alfa Mọgidi Abule Ige si ran an lọwọ, nwọn si sọ ọmọ na ni Baṣiru Akanji. Lẹhin isọmọloruko yi ni awọn obi ọmọ na fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn alabaṣeyẹ lọrun.

Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn alabaṣeyẹ ọjọ na ni awọn Ọgbẹni Yẹkinni, Dauda, S. A. Ogunbiyi, Sunmonu Lasisi, Akinde, Liasu, A. O. Ogunwẹmimọ, Rabiu, Fọlọrunṣọ Lajolu, Yinusa Baba, L. A. Oguns, Iyaafin Rafatu, Iya-Suna ati Ọgbẹni Salawu Ayinde

Ire a kari o. Amin.

## Salau Alabi ṣ'oku iya rẹ

EJIGBO.

NI ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kẹjọ oṣu kẹjọ ọdun yi ni Ogbẹni Salawu Alabi Leasu ṣe oku iya rẹ ologbe Fatumọta Ajikẹ ti o ti ku lati bi ọdun meji sẹhin. Gbogbo awọn aburo rẹ ati awọn ebi won si gbaruku ti i lẹhin. Nigbati ọjọ aṣeyẹ isinku na ti ku ola ni o ti pe awọn agba-agba Alfa ti o wa ni Ejigbo fun adura palaki o si fun wọn ni pọnun marun owo Dalailu, lehinna o tun fun wọn ni opọlọpo owo saraa ati ẹran agbo nla kan.

Nigbati o di agogo mejọ alẹ ni awọn orişirişi onilu ti o ti ranşẹ pe lati orişirisi ilu agbegbe ba de pẹlu awọn ti ilu Ejigbo paapa, nwọn si pin ara wọn ni isorisori si arin awọn alabaşeyẹ, bẹni nwọn fi ṣe aisun na moju. Nigbatị ile mọ awọn orisirişi ẹgbẹ ti o ti pe fun aseyẹ na de, ninu awọn ẹgbẹ na ni awọn Ẹgbẹ Baba rẹ Ologbe Alabi Leasu, Ẹgbe G. B. Ollivant Ẹgbẹ Ọmọnigbẹhin, Bọmọdeoku ati Ẹgbẹ Irẹpọdun.

Ọgbẹnị Salawu Alabị wa ş'ọṣọ rẹpẹtẹ pẹlu aṣọ olowo nla ati golu o si gunwa si ita bi ọba, awọn ọmọ-iya rẹ paapa Emmanuel Alabi, Şifawu Alabi, Sabitiyu Alabi si mura bakanna pẹlu, nwọn si ngnawo bi ẹlẹda fun gbogbo awọn alabaşeyẹ tị nwọn njo ati awọn onilu. O pa malu kan ati awọn ẹran agbo fun orişirişi onjẹ adidun ati orişirişi ọti ko ni iye.

Gbogbo ẹsẹ awọn onişẹ Ijọba ni o pe sibẹ ati gbogbo awọn gbajumọ-gbajumọ ilu Ejigbo, awọn Ọgbẹni G. B. Amosun, Ọmọ-ọba E. Bello ati bẹẹbẹẹ lọ ko rehin nibi inawo aşeyẹ na. Irohin ko to amojuba ni inawo aşeyẹ na, o bu-aiya o le gongo! Iru rẹ fẹrẹ ma i ti şẹlẹ ri ni ilu Ejigbo. Awọn enia ti pọju ki a ma a darukọ wọn lọ. Ehin iya o sunwọn, yio dara o.

## Ọmọ Ẹgbẹ Olomi fi kẹkẹ-olupupu pa arugbo kan lara

ỌFFA.

NI ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kedogun oṣu kẹjọ odun yi ni Malam Yahaya Balogun fi kẹkẹ alupupu Nomba KA2915 kolu iya arugbo kan, o si pa a lara pupọ tobẹ gẹẹ ti ’a na fi lulẹ ko si le tikala ara rẹ dide nilẹ. Lẹsẹkẹsẹ ni nwọn ti fi moto ayọkẹlẹ gbe e lọ si Ile-iwosan fun itọju.

Kẹkẹ na bajẹ pupọ. Mallam Yahya pẹlu Gabisiriyu Ajiboye, ọmọ Ẹgbẹ Olomi (NPC) ni nwọn jijọ gun un laseko na ti ijamba na fi şẹlẹ.

## Zaccheaus Shotunde komọjade

AGỌ-OWU, ABẸOKUETA.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kọkanla oṣu yi ni Ọgbẹni Zaccheaus Abiọdun Shotunde ṣe ikomọjade ọmọbirin kan ti Ọlọrun fi ta on ati iyawo rẹ Adekanla lorẹ ni ile rẹ l'agboile Onsa, Erunmu, nwọn si sọ orukọ ọmọ na ni Olufunmilayọ Abẹkẹ. Baba ọmọ na si fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn alabaşeyẹ lọrun.

Diẹ ninu awọn aabaşeyẹ ikomọ na ni Mọtafa Oshunrinade, Daniel Fadipẹ, Karimu Ṣobayọ, Sura Ayandele, Oluwọle, Esuọla ati opọlọpọ awọn enia ti ko si aye fun lati darukọ wọn. Ki Oluwa ki O da ọmọ na si ki O si fi ire kari gbogbo awọn alabaşẹyẹ ikomọ na o.

*Ẹ ma a ka Iwe*
*IROHIN YORUBA*
*nigbugbogbo fun*
*irohin aladun*





Inu nrun un, ko le jẹun, ko le sun ati pe irora na wọ ọ lara. O ni aran-Luruku ni.


Nisisiyi o ngbadun dada. O njẹun dada o nsun dada o si ngbadun aiye dada. O ti lo egbogi Helmezine ni.

**FI ORUMỌJU ỌJỌ KAN LE GBOGBO ARAN-EEPA INU RẸ JADE NIPA LILO EGBOGI**

**HELMEZINE**

**AGBAYANU EGBOGI ATARAN-JADE ONI-GẸẸ KAN**

Awọn Alagbata: Allen & Hanburys (Nigeria) Limited 114, King George Avenue Yaba. Telephone 44449 & 44077, Also at P.O. Box 543, Plot 7, Factory Rd. Aba.

